# GIGUN OKO OJU IRIN TO N LO SIBI IPARUN

© ***Lati Owo Moses C. Onwubiko***

> Ko si enikan ti o ni ife ti o tobi ju eyi lo, pe enikan fi emi re lele nitori awon ore re. Johnannu 15:13.

Wo ara re gege bi eni ti o wa ninu oko oju irin to n lo si ibi iparun. Gbogbo awon ero inu re ati iwo paapaa ti gba idajo iku e si n lo si ibi ti won yoo ti pa yin.

Nigba ti o ku die ki oko oju irin yii de ibi ti o nlo, odomokunrin kan duro niwaju oko naa lokankan. O n ju asia pupa kan lati da oko yii duro. Eni to n dari oko naa gbiyanju lati da oko duro. Awon osise inu oko yii beere ohun ti okunrin yi nfe o si so fun won pe oun fe lati gba iku gbogbo awon to wa ninu oko naa ku! O so pe! Mo wa lati mase je ki won pa yin mo," Awon osise oko yii sare lo so fun onidajo to da ejo iku fun won oun ti oju won ri.

Leyin ti adajo ti fi oro wa okunrin naa lenu wo tan, adajo gba lati je ki okunrin naa ku dipo awon ti o wa ninu oko naa, nitori pe ko ni akosile iwa ese kan tabi iwa odaran kankan. O je eniyan ti ko ni abawon gege bi akosile igbe aye re ti fihan, sibe o setan lati fi ara re sile lati je iya ti o to si won.

## A FI IFE RE FUN AWON TI A DA LEBI HAN

Ni oju re ati awon ero oko yooku ti a fi da lebi ni a mu okunrin yii si a si lo pa a. A fi iya je asi fii se eleya loju gbogbo yin. Mo fe ki o fi asiko die sile lati ronu lori ipo yii. O je ohun to soro lati gbagbo pe okunrin le fi ara re sile fun ijiya awon odaran kan.

Nigba ti odomokunrin yii wa lori iji ti a ti kan an mo fun iku, o ke rora ninu ibanuje fun iranlowo, sugbon ko ni idi re? nitori ki a le gba awon to wa ninu oko oju irin naa kuro lowo iku. Adajo na wa pa ase ohun ti awon ti o wa ninu oko oju irin naa yoo se gege bi imoore fun okunrin ti o ku nitori won yii.

## OTITO NAA

Kii se itan kan lasan ni eyi; A fi se akawe ni, Bibeli so pe;

> Gbogbo eniyan ni o ti se, ti o si kuna ogo Olorun.
> (Romu 3:23)

Iku ni ere ese (Romu 6:23a)

Idajo yii lati ile ejo to ga ju lati orun fi idi re mule pe gbogbo eniyan ni o jebi ese ti o si ye ki a ran sinu ina ileru, eyi nipe ki a pin in niya kuro lodo Olorun titi lai. Gbogbo eniyan patapata ni o wa labe idajo Olorun – eyi ni oko oju irin ti o nlo sibi iparun.

**IGBIYANJU ENIYAN**

Bibeli ti pese idahun sile lati tako awawi eniyan niwaju Olorun. Enikan le so pe, "mo n gbiyanju lati se rere." Bibeli so pe:

> Ko si enikan to nse rere, beeni Ko si enikan. (Romans 3:12b)

Nibo ni enikan ti bo kuro ninu eyi? Elomiran tile le so pe, "Mo ti ngbiyanju lati pa ofin Olorun mo." Bibeli tun dahun pe:

> Enikeni ti o ba pa gbogbo ofin mo sugbon ti o ru okan, o ti jebi gbogbo re (Jakobu 2:10).

Ibeere nipe: Melo ni a le pa mo ninu ofin Olorun ki Olorun to gba eniyan lo si odo re? 'Gbogbo awon ofin ni! Asise kan ti aba se pelu ofin ti so eniyan di arufin fun gbogbo ofin naa. (Jakobu 2:10). Taa ni o le ko gbogbo ofin ja? Taa ni o le se laarin ojo kan, ose kan tabi odun kan lai ru okan nini awon ofin Olorun? Otitio nipe;

> Ko si eni ti o mo, ko si enikan (Romu 3:10b)

Eniyan tun le so saaju si pe oun n gbiyanju lati gbe igbe aye otito. Bibeli tun so pe:

> Gbogbo wa si dabi ohun aimo, gbogbo ododo wa si dabi akisa elegbin. (Isaiah 64;6a)

Eleyi kii se irohin rere fun enikeni. Gbogbo igbiyanju eniyan lati ri oju rere Olorun ni a ti pare. Ki ni o ku fun wa?

***Ko si ohun kan!***

Nje ikosile lati odo Olorun yii tumo sipe. Ko si omo eniyan ti o le lo si orun? Bee ko. Ohun ti o tumo si nipe asan ni gbogbo ipa eniyan. Ireti kan soso tabi ona abayo kan soso naa ni oore-ofe Olorun.

**ENIYAN NINU IPO AINIRETI RE**

Olorun gege bi Oludasile je mimo. O je olooto ati Olorun onidajo ododo. Ninu iwa mimo re, ko le darapo mo ese tabi elese (I John 1:5). Gege bi Olorun olotito, ko le je ki elese lo lai jiya. Ko seese ki einyan ti kope ni ibasepo pelu Olorun to pe. Ko see se pelu agbara eniyan.

> Eniyan ni eyi soro fun; sugbon fun Olorun, ohun gbogbo ni sese. (Mattiu 19:26b)

Eniyan ninu igbiyanju re ko le te Olorun lorun pelu iwa mimo Re. Enikan le ro pe oun dara, sugbon Olorun so pe: ko si eni ti o nse rere (Romans 3:12b). Enikan le maa ronu pe oun ni gbe igbe aye rere. Olorun so pe, ko si eniti o mo" (Romans 3:10). Elomiran nronu pe a le da oun lare nipa pipa ofin Olorun mo. Olorun dahun pe:

> A ko da eniyan lare nipa ise ofin (Galatia 2:16)

Ko si ona abayo fun eniyan lati bo lowo idajo ododo ti Olorun eyiti a gba kale lori gbogbo eniyan (Romu 3:23). Ko si ona abayo kuro ninu idajo re. Gbogbo eniyan ni a tida lebi ti a si ti ran lo sinu ina ileru. Ko si bi eniyan ti le gbiyanju agbara re, to le bo lowo idajo yii.

Nje eyi wa tumo sipe ko si ireti lati bo kuro lowo idajo Olorun? Beeko. Olorun ni eto kan soso fun ona abayo. Eto naa ni ti oore-ofe. Tele eto oore-ofe yii ki o si bo tabi ki o ko o sile, ki o si dojuko ibinu Olorun (Johannu 3:36).

**IROYIN RERE NAA.**

Nigba ti eniyan ngbiyanju lati bo kuro ninu idajo Olorun nipa igbiyanju ara re, enikan wa lati gba a. Okunrin naa ni Jesu Krisit, omo Olorun. O fi ara re sile gege bi enikan soso ti ko ni aleebu ti o to lati ku fun eniyan. Johannu onitebomi so nipa okunrin yii;

> Wo o odo agutan Oluwa eni ti o ko ese araye lo
> (Johannu 1:29b)

O gba iya ese wa je.  Aposteli Peteru fi kun un pe:

> O (Jesu Kristi) ru ese wa fun ara re lori agbelebu
> (I Peter 2:24)

Paul Aposteli kede pe:

> Sugbon Olorun fi ife oun tikarare han si wa, nigba ti awa je elese, Kristi ku fun wa. (Romu 5:8)

O ti san gbese fun ese wa leekan (Heb.9:12).

**BAWO NI IHINRERE YII TI DARA TO?**

A ti san gbese idajo iku eyi ti a da eniyan.  Idiwo ti o wa laarin Olorun ati eniyan ti di mimu kuro.  Ese mu iyapa wa laarin eniyan ati Olorun (Isaiah 59:2).  Jesu Kristi mu iyapa yii kuro nipa iku re lori agbelebu.

Egun ti o wa lori eniyan nitori aile pa ofin Olorun mo ni a mu kuro nipa iku yin.  Kristi ra wa pada kuro ninu egun nipa didi ogun fun wa, bi a ti ko o pe:

> Egbe ni fun enikeni ti a kan mo igi (Galatia 3:13b)

Jesu Kristi nikan ni o seto alaafia pelu Olorun  (1 Timoteu 2:5).  Isoro omo eniyan nipa ailera ofin Olorun mo ati aini agbara eniyan ni a mu kuro nipa iku Jesu lori agbelebu.

> O si ti pa iwe majemu ni re, ti o lodi si wa, ti a ko ninu ofin, eyi ti o lodi si wa.  Oun ni o si ti mu kuro loju ona, o si kan an mo agbelebu.  (Kolose 2:14)
>
> Nitori oun ni alaafia wa,  eni ti o yi se mejeeji ni okan, ti o si ti wo ogiri ikele nni ti be laaarin; o si ti fi opin si ota nni ninu ara re, ani si ofin ase won nni ti n be ninu ilana.
> (Efesu 2:14, 15a.)
>
> Sugbon Olorun fi ife Oun paapaa si wa han ni eyi pe, nigba ti awa je elese, Kristi ku fun wa. (Romu 5:8)

**ONA ABAYO TI KO SEE GBAGBE**

Ranti nipa oko oju irin ti o n lo sibi iparun. Leyin ti okunrin ti ko lese naa ti gba lati ku fun awon ti o wa ninu oko, ohun ti adajo so nipe awon ti o ba fee jade kuro ninu oko naa gbodo jade lati enu ona kan soso. Enu ona yii wa lati bowo fun emi eni ti o ku fun awon eniyan yii. Enu ona ti ko se o gbagbe ni eyi. Ronu nipa ohun ti o le je ero okan awon ti a ti dajo iku fun ti won si gba lati gboran si ase adajo nipa gbigba ona abayo si omniran.

Ki a fi se akawe, Olorun ti pa ase lati iyara igbejo re ni Olorun. Idajo kan ti o tona niwaju re nipe ki a wole lati enu ona kan soso. Ko si ohun ti a le se lati yi ipinnu yii pada. Ofin Olorun daju. Awon ero wonyi ni lati jade lati enu ona kan soso. Enikeni ti o ba fe lati lo si orun gbodo gba ona ti Olorun la sile.

**ENU ONA SI ORUN**

Jesu Kristi fun ara re so nipa idajo Olorun pe:

> Emi ni ona, otito ati iye, ko si eni ti o le wa si odo Baba (ni orun) bikose nipade mi (Johannu 14:6)

Luku fi kun un pe:

> Ko si igbala lodo elomiran, nitori ko si oruko miran labe orun ti a fi fun eniyan nipase eyi ti a fi le gba wa la. ( Ise Awon Aposteli 4:12)

Eyi tumo sipe bikose nipase Jesu Kristi nikan ko si eniyan ti yoo lo si orun tabi ti yoo ri igbala. Jesu Kristi fun ara re so eyi daju. Ko si ona eburu kankan. Olorun mo nkan ti o so 'Gba" enu ona wole ki a si gba o la tabi ki a ti ileku mo o lati ma le lo si orun titi lae.

**BI O TI LE RI IGBALA**

Ona kan soso lo wa to lo si orun, ona naa ni nipase Jesu nikan. Jesu Kristi so pe:

> Emi ni ilekun, bi enikeni ba wole nipase mi, a o gba a la (John 10:9a).

Bawo ni eniyan se le gba enu ona ti ko ri wole? Niwon bi o ti je pe Jesu ni ilekun naa, ona kan soso ti eniyan le gba wole naa ni igbagbo ninu Jesu nikan. Ki ni idiwon igbagbo yii? Kekere ni 'gege bi koro eso mustardi" (Matt.17;20).

**Apejuwe igbagbo:** Nini majemu laelae, awon omo Israeli saigboran si Olorun. Olorun ran ejo apanirun si won. (Numbers 21:6). Ejo na ge won je, o si pa opolopo. Awon omo Israeli jewo ese won fun Olorun. Olorun iba pa won re kuro lori ile, sugbon ko se bee. Dipo bee, Olorun so fun Mose pe:

> "Ro ejo amubi ina kan, ki o si fi i sori opa gigun kan, yoo si se, olukuluku eni ti ejo ba busan, nigba ti o ba wo o, yoo ye. (Numeri 21:8)

Mose se gege bi Olorun ti paa lase fun un. Mose tele ilana ti Olorun fun un. Ohun ti o ku ni ki awon omo Israeli naa tele ase ti Olorun pa fun won nipase Mose. Won ni anfaani lati yan boya ki won tele ohun ti Olorun so tabi ki ejo naa pa won run.

Looto, gbogbo awon ti ejo naa sa je ti won lo si siyemeji lori oore-ofe Olorun tabi ogbon re tabi se awoye lori oore-ofe Olorun ninu ilana ti o fun won, sugbon ti won wo ejo ti Mose, gbogbo won ni won ye. (Numbers 21:19). Iyanu alaileeso ni ooreofe Olorun fun awon omo Israeli, o rorun to bee ti omode ati agba le wo ejo Mose ti won si y

Ko si ise kankan ti o ro mo ikilo oore-ofe. Ko si ileri kankan ti Olorun nfe, ko si ojuse kankan, ko si ipinnu ijo tabi apejopo kan, ko si iribomi kankan tabi idamewa. Ore-ofe nla ni eyi lati agbala Olorun to nifee. Olorun kan naa ti o fun Mose ni ikilo ni opolopo odun seyin ti se eto lati wa ona abayo si isoro omo eniyan.

**OMO OLORUN TI A GBE SOKE.**

> Gege bi Mose ti gbe ejo soke ni aginju bee naa a gbodo gbe omo eniyan soke to bee ti enikeni ti o ba gba a gbo yoo ni iye ainipekun (John 3:14-15)

A gbe Jesu soke ni ori agbelebu nigbati akan an mo agbelebu. Gege bi awon omo Isreali ti wo ejo Mose loke, iwo naa le wo agbelebu pelu igbagbo ninu Jesu Krisit ki o si ni idaniloju igbala nipase Jesu Kristi nikan.

A so pe ki awon omo Israeli wo ejo ni aginju. Ki ni ere to wa ninu wiwo? Ko si ere kankan. Ni ibi agbelebu, igbagbo lasan ni. Nje ere kankan wa ninu gbigbagbo? Ko si. Ere je ti Jesu Kristi. Ipinnu Olorun lati tu awon eniyan sile ninu aginju nigba naa rorun. Bakan naa ni ipinnu Olorun lati gba eniyan la lonii. Olorun mu ki nnkan rorun fun awon eniyan, sugbon esu ati awon omo ogun re mu inira wa fun eniyan ni lati mase je ki eniyan ri igbala. Oro igbala je nnkan ti o rorun. Oda lori igbagbo ninu Re" kii se" igbagbo ki a site o bomi" tabi gbagbo ki o si di omo ijo", kii se gbagbo ki o si tun gbagbo" kii se gbagbo ki o si fi Jesu se Olorun." Olorun ni lati igba aye wa. Ko si ohunkohun ti a fi kun igbagbo. Oro Olorun lori igbala daju pe:

> "Eni ti o ba gba omo gbo, o ni iye ainipekun: eni ti ko ba si gba omo gbo, ki yoo ni iye; sugbon ibinu Olorun n be lori re" (Johannu 3:36)
>
> 'Nitori Olorun fe araye to bee geee, ti o fi omo bibi Re kansoso fun wa, pe enikeni ti o ba gba a gbo ma ba segbe, sugbon ki o le ni iye ainipekun." (Johannu 3:16)
>
> "Sugbon wonyi ni a ko, ki eyin ki o le gbagbo pe, Jesu ni i se Kristi naa, omo Olorun; ati ni gbigbagbo, ki eyin ki o le ni iye ni oruko Re." (Johannu 2:31)

**ODODO OLORUN**

Nje Olorun le paro? Bee ko.

> Olorun kii se eniyan ti yoo fi paro (Numeri 23:19)

Bi Olorun ba so pe "enikeni ti o ba gba omo gbo yoo ni iye ainipekun ti o si ri bee (Johannu 3:36). O mo ohun ti o nso. Bi o ba so pe "enikeni ti o ba gba ohun gbo ko nii segbe ti o si se bee (Johannu 3:16). O tumo sipe enikeni ti o ba fi igbekele re sinu Jesu ko ni lo si orun apaadi. Ko ju bee lo. Lona miiran, bi Olorun ba so pe "Enikeni ti o ba gba Jesu Kristi gbo ti o si gbaa bi Olugbala re, ti a si tee bomi, ti o si fi ara re jin fun un ko ni

segbe”, osan fun o ki o se awon nnkan wonyi ti o ba fee ni iye ainipekun. Ironu nla ni eleyi, ohun kan daju ninu oro re:

> “Gba Jesu Kristi Oluwa, ao si gba o la.” (Acts 16:31)
> oore-ofe Olorun to nsise ni eyi je.

**IPINNU RE TI O SE PATAKI JU**

Ni akoko yii, o le se ipinnu ti o ga ju ti yoo mu ayipada ba igbe aye re laelae. Bawo ni? Nipa siso fun Olorun pelu gbigbe ohun soke tabi siso ni kelekele fun Olorun pe o gba omo Re eyi ti a gbe soke lori igi agbelebu lati ku fun ese mi. Nigba ti o ba ti fi igbekele re sinu Jesu nikan, o ti gboran si ase Olorun. Lati akoko naa ni ise iyanu igbala ti bere. Akoko ti o se pataki pupo ninu aye re ni eyi. Aye titi afi aanu ati iyanu nla ra pada nipa oore-ore Olorun.

> Oore-ofe ni a fi gba yin la” (Efesu 2:8a).

Kin ni awon ise iyanu yii? Olorun olotito ti paaro iwa eeri ati aisooto re pelu otito tire (Romu 3:22) eyi ni ifese mule idajo re. Lara ohun ti o fun o ni iye ainipeku Re. (John 3:36). Lati akoko naa lo ni o ti gba otito Olorun. O si ni aye re ninu aye Re. Ebun oore-ofe Olorun fun igba akoko yi ti fun o ni ooreofe lati maa gbe pelu Olorun titi lae.

Kin ni ohun ti o se lati gba okan kan ninu awon ebun yii? Ko si. Fun idi eyi o le so pe o ko se ise fun igbala eyi ti Olorun fun o bikose ooreofe re. Eyi tumo sipe o ko le se ohunkohun lori ohun ti Olorun ti se. Ohun ti Olorun ba se ko se e yi pada. (Romu 11:29).

Ihinrere naa niyi. Anfaani naa ti de. Tire ni lati se ipinnu. Nipa igbagbo ninu Kristi ni igbala ti wa, ninu Jesu Krsiti nikan. Ona abayo kan soso ti Olorun seto re niyi. Gba ooreofe yii ki asi gba o la tabi ko oore-ofe yii ki o si lo si iparun aiyeraiye.

**ETE OLORUN DAJU**

> Eni ti o ba gba omo gbo, o ni iye ainipekun; eni ti ko ba si gba omo gbo, ki yoo ri iye; sugbon ibinu Olorun n be lori re.: (Johannu 3:36).

Tire ni lati se ipinnu; nitori naa, a gba adura yi fun o.

***Baba orun, a dupe fun ebun ofe, omo Re ti a fi rubo lori agbelebu. Adupe pe o mu ki igbala rorun fun enikookan. Agbadura fun enikookan ti o ti ka iroyin rere yii sugbon ti won ko ti se ipinnu aiyeraye. Agbadura pe won yio ni oye ti o jinle nipa gbigba tabi ki ko oore ofe Re sile. Baba, a be o, fi owo kan enikookan ti ko tii gba Kristi gbo lati ma se asaro lori oro yii, ki won si gbagbo. Ni oruko Kristi. Amin.***

**FUN AWON TI O TI GBAGBO**

Olorun fe ki o dagba ninu oore-ofe (II Peter 3:18) ofe ki o maa poungbe eko ti o ye koore. ( I Peter 2:2). Bi o ba fe lati maa gba iwe yii ati awon iwe miran ti o le ran igbe aye emi re lowo lofe e, o le ri adiresi wa leyin iwe yi.

***Ebe adura***: (Fun awon ti o gbagbo)

> Fi ara re sile fun adura, tesiwaju ninu re pelu emi ope (2 Kolose 4:2)
>
> Ipa ti aburo olododo n ko lagbara pupo (Jakobu 5:16b)
>
> 'Ju gbogbo re lo, ema gbadura fun wa pelu, ki Olorun le si ilekun fun wa fun ore naa, lati maa so ohun ijinle Kristi, nitori eyi ti mo se wa ninu ide pelu" (Kolose 4:3)

**RA OTITO, MASE TA A**

(Owe 23:23a)

Nje o mo pe eko Bibeli to jinle je eyi ti o niye lori fun ohun oso ti emi? Looto ni, itan ijo Olorun ti fihan bi o ti nira to lati ri eko ti o jinle paapaa laarin esin Kristiani lode oni? Nitori naa nigba ti Olorun ninu opa oore-ofe Re ba n mu wa lo sibi oro otitio pe, o ye ki a mo riri oore ofe yii. Bibeli dabi apoti oro ninu eyi ti o ti le ni oro pupo, lati jere opolopo ayo nipa aye, ibasepo ti o dara, igbeyawo, okowo, ki asi gbadun ibukun lojo oni ati lojo iwaju; nitori naa, "ra otito" (fi ese mule ninu oro naa)

> "Nitori pe ogbon dara ju ohun ogo lo, ko si ohun kan ti a le fi we" (Owe 8:11)

**Otito:** Nitori eyin ko si labe ofin SUGBON labe OORE-OFE (Romu 6:14b)

Grace Evangelistic Ministries
P.O. Box 583
Jos, Plateau State
Nigeria

Darlington
dekwae@yahoo.com